**Akiyesi**
A nfẹ aṣoju ni awọn ilu wọn i:- Iseyin, Jos, Ondo, Ilesha, Ibadan, Ogbomosho Saki, Kaduna, Ijẹdẹ Ọyọ, Ile-Ifẹ Zaria,. Gbọgan, KABBA Otta, Ilaro, Aba, IKIRE kọwe si Olotu 16, Bamgboṣe Street. Phone 21985

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Oja kota!** E ma Polowo Oja yin sinu Iwe Irohin Imole

VOL. IV No. 200 MONDAY MARCH 27 — APRIL 3 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Omode kan mu igo epo Karosini kan tan, o si ku lesekese

EKO

OMODE KEKERE ỌMỌ ỌDUN META KAN RI TI OGBON RE NMU ỌTI OYINBO (BEER) O ṢE AKIYESI WIPE INU IGO NI O TI NBU ỌTI NA NI ON PAPA BA SARE WỌ IYARA IYA RẸ LỌ NI O BA GBE IGO EPO KEROSINI (KEROSINE) KAN O SI MU YO BAMUBAMU.

Ọmọdebinrin yi ti orukọ rẹ njẹ Ademọla Ade ti o si ngbe 23 Akọbi Crescent ni Surulere pẹlu awọn Obi rẹ ku si ile Iwosan nla ti ilu Eko ni kete ti o mu epo na tan. Iku Ọmọde yi jẹ agbanyanu ati ọfọ nla fun awọn Obi rẹ ati gbogbo alabagbe rẹ nitoripe gbogbo wọn ni wọn ya nyọ lati ri Ọmọde arẹwa yi ti o ba nṣere ni ode gbangba.

Iya ọmọde yi Mrs. F. Ade sọ wipe on wa ni ọdẹdẹ pẹlu awọn alejo ati ẹgbọn ọmọde yi ati Ologbe ọmọde yi nṣere lẹgbẹ kan, nibi tabili. Ti ẹgbọn rẹ si nmu ọti. Beer, nigbati ọmọde yi se akiyesi wipe ẹgbọn on nbu nkankan lati inu igo ti o si nmu ni on na sare rọ wo iyara iya rẹ lo ti o si ki odidi igo epo kerosini kan mọlẹ ti o si mu yo kedẹrẹ. Jijade ti ọmọde yi jade lati inu iyara ni iya rẹ ṣe akiyesi wipe oju rẹ ti yipada ni agbari rẹ ti inu rẹ ṣe ri rogodo ti o si ndan ni wọn ba sare gbe lọ siỌdan ile iwosan ṣugbọn epa ko ba ọrọ.

Awọn Oniṣegun gbidanwo ṣugbọn Ọlọrun ko fun wọn ṣe, wọn du tifi afi igbati ọmọ na lọ jẹ ipe Ọlọrun Ọba.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸRIN

**MOGBAYI BABY MIXTURE**
OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni aṣepe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ odun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribi ribiti o ti nṣe.

MOGBAYI BABY MIXTUREjẹ egbogi to, dara fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu Ọmọde, jẹdi jẹdi, kokoro oṣi ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun ionfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ti awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afọjuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko ṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupo, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere re jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*
**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

6, Balogun Street. West Lagos Nigeria Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 204247

## Adajo Kotu Sapele da Oloye Okotie-Eboh lebi

Adajọ Kọtu nla ni ilu Sapẹlẹ da Oloye Okotie-Eboh ti iṣe akapo owo Ijọbọ lẹbi, fun ẹsun wipe owọ ilẹ onilẹ laigba aṣẹ, o si huwa ti o le da ijọgbọn silẹ nilu. Awọn enia meje ni adajọ na da ẹjọ yi le lori o ni ki ẹnikọkan wọn lọsan Pọun mẹwa, mẹwa tabi ki awọn lọsi ẹwọn oṣu kọkan. Orukọ awọn enia meje na niwọnyi, M. Usi M. Onwuka, O. Umeb, A. Ibeasi, P. Egenti, E. Nwakwo, O. Nwafor. A gbọ wipe ọkuntin kan ti nwọn npe ni Oroko lo ni ilẹ ti a wi, ti o si ti bẹrẹsi kọle sori ile na, o si ti bo ni panu, ki Okotie-Eboh to de ibẹ, o si nwo gbogbo ile na palọ, Adajọ ni on fun Oloye Okotie-Eboh ni aye ọjọ mẹrinla ki o fi tun Ile na kọ, ki o si bo o ni panu. Awọn agbẹjọro meji nwọnyi lo wa fun Oloye Okotie Eboh Oloye H. O. Davies Q.c ati Ọgbẹni W. E. Egba. Oloye Davies sọ wipe ẹjọ ti adajọ na da fun on ko tẹ on lọrun. A gbọ wipe awọn enia meje ti adarukọ pẹlu Oloye na ni awọn ti o tu panu ile na, ti nwọn hu ilẹkun ile titun na ti nwọn si fa windo ya.

Oloye Davies sọ fun adajọ Ọgbẹni Kester wipe ẹjọ ti o da fun Oloye Okotie Eboh, on ko fi ara mọ rara, on yio gbe ẹjọ na lọ siwaju kọtu Arotunro nilu Eko, ati wipe ẹjọ ti adajọ nada, ki Ijọba si ba on gbe ẹsẹ le na ki Oloye Okotie Eboh maiti ṣe ohun kan si ile na.



Oloye Okotie Eboh

Adajọ na sọ wipe on fi ara mọ eri ti awọn alatako ọrọ jẹ, o han gedegbe ninu akọsilẹ ti o mbẹ niwaju kọtu wipe Ọgbẹni Ororo lo ni ile yi, lojoti awọn enia meje tia darukọ loke yi fi wa wo ile na palẹ.

Adajọ na sọ wipe, on ko gba ẹri ti Ọgbẹni E. Dalẹ ti o ta ilẹ ile na fun Oloye Okotie Eboh gbọ ninu eyi ti o sọ wipe Ọgbẹni Ororo lo ti ntọju ile na ri. Gbolohun asọ ti wa larin Ọgbẹni Ororo ati Ọgbẹni E. Dale lojo pipẹ lori ẹniti o ni ile na.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸRIN

O BERE LATI OJU EWE KETA

aiṣ, ti mo ba kuro nibe sugbọn laila, emi ọrọ na gun lọ titi, mo ripe ere ọdun tibẹ dunju eyi ti mo ti ko lọ wẹ ri lọ. Adura mi nipe Olọrun Olodumare yio jẹ kale mi ri ọpọlọpọ ọdun ṣe laiye, ero ngba wa si rere ki Olọrun alanu ti kalara ki o ma sai ma ba wọ, ti idi ohun rere ti mbọ nakalẹ amin. Agẹyi ṣamọdun, a ṣamọdun ṣe emi fun gbogbo wa o (Amin o).

Emi ni,
S. A. Aro,
Eko.

## Owe Yoruba

Adiẹ njẹkẹ, o dmu omi, o nje ẹran, o ni, on ko ni ehin, awọn to ni ehin nkọ, kini nwọn fi nṣe?. Ikun nje ẹpa o nrodi, Ikun ko mọ wipe ohun ti o ldun lo npa ni.

Eniti a ni ki o kinni lehin fi ẹgun si owọ, eniti a ni ki o fọ ni lojo ti ata si ẹnu, ẹniti a pe ki a fi ẹhin ti ki a mu didun ọsan, ganin-ganin lo nfun ni mu.

ADVERT No. 33

## FEDERAL MINISTRY OF FINANCE LAGOS

PRESS NOTICES

STAMP DUTIES ORDINANCE (Cap. 191)

The Ministry of Finance announce that with effect from the 1st of April, 1961, the rates of Stamp Duties in the Schedule to the Stamp duties Ordinance (Cap. 191) have been revised in general the rates have been increased by 50% but the rates on certain items have not been changed The new rates will be published in the Federation of Nigeria Official Gazette.

Ministry Of Finance,
Lagos.

ADVT 35

COMMISSION OF INQUIRY

## Customs and Excise Exhibits

It is notified for general information that the above Commission which starts its sittings on the 18th day of March 1961 in the Conference Room, Mosaic House, Lagos, invites all desiring to give evidence before it to send in to the Secretary, whose address is below, written memoranda or, in lieu of memoranda, written applications for permission to appear to give evidence. Written applications for permission to give evidence must clearly define the subject matter of the proposed oral testimony. The memoranda or written applications should reach the Secretary before the 25th day of March, 1961.

The Commission intends to study these applications and then, as soon as conveniently may be, to issue written invitations to all those whom the Commission considers are likely to be able to help with the Inquiry to appear before it.

The Commission's terms of reference are:

(a) To determine what exhibits were recovered by officers of the Board of Customs and Excise in the course of their investigation into an alleged contravention of the customs laws by the movement from Port Harcourt Wharf in June, 1957, of a consignment of 352 bales of second-hand clothing ex the M.V. Obuasi, R57/242 of 13/6/57 and the whereabouts of such exhibits.

(b) To determine if in the handling of the said exhibits any person has acted improperly.

(c) To make such recommendations as may be considered appropriate.

(C. NNABEZE)
Secretary to the Commission,

*17th March 1961.*
*via Permanent Secretary,*
*Fed. Ministry of Finance,*
*Lagos.*

## IROHIN IMOLE

*16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.*

**Phone 21985**

### TOWN & CIRCULATION

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Ibadan | 600 | Maiduguri | 200 | Ado-Ekiti | 500 |
| Ghana | 600 | Tatuwada | 100 | Fiditi | 300 |
| Ilorin | 210 | Jebba | 300 | Ọtta | 300 |
| Ifo | 200 | Ngru | 200 | Ikire | 600 |
| Otun Oro | 210 | Bauchi | 100 | Calabar | 100 |
| Iseyin | 500 | Ajaṣe-Ipo | 500 | N. Niger | 100 |
| Jos | 500 | Onitsha | 300 | Jẹmi | 100 |
| Accra | 500 | Abẹokuta | 200 | K. Namuda | 100 |
| Ondo | 500 | Ivory-Coast | 200 | Kafansha | 100 |
| Ilesha | 500 | Ọyọ | 200 | Minna | 100 |
| Kabba | 200 | Agege | 200 | Adamawa | 100 |
| Ogbomoṣọ | 200 | Ikorodu | 200 | Bidda | 100 |
| Ikennẹ | 200 | Offa | 250 | Enugu | 200 |
| Ijẹbu-Igbo | 200 | Ibara | 400 | P. harcourt | 150 |
| Owọ | 225 | London | 400 | Igbẹssa | 550 |
| Ijoko | 200 | Kaduna | 400 | Ilaro | 500 |
| Iwo | 500 | Ile-Ifẹ | 400 | Bádagry | 100 |
| Ikarẹ | 300 | Ijẹbu-Ode | 400 | Ajilete | 100 |
| Shaki | 300 | Akurẹ | 300 | Ado | 200 |
| Ijẹbu Omu | 200 | Shagamu | 300 | Ẹdẹ | 600 |
| Kano | 200 | Gbogan | 300 | Okiti -Pupa | 500 |
| Ijẹdẹ | 250 | Oshogbo | 500 | U.S.A. | 50 |
| Aba | 200 | Zaria | 600 | Lagos | 5000 |



ADVT. 36

# Ministry Of Communication's LAGOS.

## Overseas parcel post rates.

Revised rates will be charged for the transmission of parcels to Overseas Countries with effect from 1st April, 1960. Full details are contained in Federal Government Notice No. 392 of 16th of March, 1961 and may also be obtained at any Post Office.

The revision is occasioned by Nigeria's impending membership of the Universal Postal Union, which regulates international Postage rates, and brings Nigeria's rates into line with the Union's current regulations.

Ministry of Communications,
Lagos.

## Akinfosile da lamoran wipe ki ede Hausa je Olu Ede ile Naijiria

Ogbeni Olu. Akinfosile ti ise Alakoso ile ise yi ti iwe tanete silu okere da lamoran ninu ose ti o koja yi wipe ki Ijoba Naijiria so ede Hausa di olu ede ile Naijiria ti enikeni yio ma so gegebi ati nso ede Oyinbo ninu ohun gbogbo. Alakoso yi so oro yi ni ilu Oyinbo nigbati oniu awon omo Akeko ninu sere orore Akinfosile so wipe idiro ti emi enia damoran yi wipe ti nso ede Hausa edepo pupo ni jakejado ile enia dudu nitori idi eyi na gbayi ju ede miran lo.



Olu. Akinfosile

O se alaye bayi wipe ko ye ki o je wipe Ijoba apapo ko ni agbara lati yan ede kan ni olu ede nitori wipe yio nu ede aiyede wa larin opolopo enia. Siwaju si Akinfosile tun wipe ile Naijiria yio tun duro sinsin ju miran bi o ti ndu lore ati wipe ilu yi yio fi apin si iyato awo ara wa depo ti oje wipe alawo funfun ki yio so wipe on yato si alawo dudu.

Lakotan Alakoso yi soro nipa ise iranlowo gidigidi ti ile Naijiria yio ma se fun awon Orile ede ti o ba nfe tiwa ti won si le ran wa lowo o so wipe asiko ti to ti o ye ki gbogbo orile ede agbaiye fi ipinnu si iwa imotaraenienikan larin orile ede si orile ede.

## Odaran kan fe fi agbara ba Obinrin lopo.

OFFA:- Lenu lolo yi ni Odomodekunrin kan ti oruko re nje Olusegun Falana fe fi tagbaratagbara mu omodebinrin kan ti oruko re nje Ebun Aibi lopo nipa.

Olusegun Falana yi je ese odun metalelogbon o si nse ise labe Ijoba Railway ni Loco Offa omodebinrin yi wa ni ... gegebi ati segbo lenu awon olopa ti o nse iwadi oro na, gege bi ojo ti mbinrin na fe ni iwe, odaran yi pe on o si so pe on ni iwe kan lati fi gbe nitori na ki on si tele wa gba iwe na nitori pe iwe ti o je pataki ni iwe na. Lehin igbati omodebinrin yi wo inu ile tan ni odaran yi ba ... pe ... da lara ti oju odaran yi si ti yi pada ... omobinrin ko gba gege bi odaran yi ti nse; lehin opolopo iyonu ati ijakadi ala omobinrin yi ko si le farati mo, ni omobinrin yi ba pinu lohan re lati be sile lati oju ferese lori oke petesi (up stairs)

Nikia iroyin ti omo yi be sile ni o ba gba ona ile awon olopa lo. lenu owo awon olopa ba te odaran yi ti awon olopa si ti mu odaran na lo si ile ewon remand biti odaran na wa titi asiko ti a fi nte iwe wa yi lowo. Beni awon olopa si nse iwadi oro re lowo-lowo bayi.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985, Olotu: E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street Surulere, YABA.

O BERE LATI OJU EWE KINI

Ni gbogbo ojo-mobo ti isele nla yi se ati titi di oni ni awon alaba kedun ti nwo nile awon obi omode yi.
AWA ONIWE IROHIN IMOLE KI AWON OBI OMODE YI PELE OLORUN YIO PARO IT ANFANI FUN WON.

Adajo na tun fi enu kan oro Iyafin Comfort Ajale ti o so wipe, on ti ngbe inu ile na ri, on si baya re lowo ogbeni Ororo fun osu marun, eyi fihan wipe Ogbeni Ororo lo ti ni ile na sti nigbati nwon fi nwo luly.

Gegebi ofin Ijoba ti lo ninu egiti nwon fi Oloye Okotieboh sun, ki a so pe emi ni mo ni ile na, koto fun igba ara eni sile. Oye ni lenu lati gbo wipe iru enia bi Okotieboh mba enikan se ariyanjiyan eniti o ni ile o wa didelo gba ile na pelu agbara lati ti ofin Ijoba se.

## Abiyamo kan bi Omo tan, o gbe e sonu si oju agbara



EKO :- Ose! eniti o lori, koni fila, eniti o si ni fila ewe, on ni ko lori yi. Ha! abiyamo miran ma kuku daju ojo. Ni owuro ojo Sunday ti awon Musulumi nwo janrore lo si Mosalasi Odun lati le fi ope fun Olodunmare ti o da won si lati odun tio koja ti nwon si ri opin awe ti odun ni, ti awon Kiriyo si nse iranti ijiya Jesu ni Jerusalem' ibe ni Olorun fi Omo titun ta Obinrin kan lore, ti obinrin buruku na si lo gbe omo jojolo na junu sinu gota, Okunrin Olopa kan ti o ntoju awon ti o nkoja lo fi rifiri bere si gburo igbe omo titun jojolo lati inu oju agbara ti o wa ni Anikantamo nitosi ile Ologbe Anduru Olopa yi ko le lo mo, o si nwa ona lati gba emi omo kekere jojolo na la, Ki o si to di wipe moto alabapo de lati gbe omo na nawon agogo mewa owuro, omo na ti ku

Ibe ni Obinrin kan si bu si ekun, o wipe ibase wipe omo na ko ku ni, se on iba gba a to, on a si fi se omo gegebi on koitibimo ri.

Ha! o ri nkan, winni-winni loju orogun, ejiworo loju iya re, Omo ko alaso, ile hun! eniti o lori ko ni fila, eniti o si ni fila ni ko lori yi.

## Akiyesi Pataki

Enikeni ti o ba ngbe agbegbe ilu wonyi Mushin Iju Odi Olowo, Ikeja, Owode, Otta, Oshodi, Ifo, Atan ati Onibuku, ti o ba si fe ra iwe "IROHIN IMOLE" ki o lo si odo asoju Irohin Imole Ogbeni Ebenezer Folarin ti o ngbe No 36 Buari Street Olorunsogo Mushin.